# IJỌ TI O WÀ NI KỌRINTI

**1 Kọrinti 11:18-22, 12:1-31; 14:1-40**

**ẸKỌ 392 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori ti o ti rà nyin ni iye kan: nitorina ẹ yin Ọlọrun logo ninu ara nyin, ati ninu ẹmi nyin, ti iṣe ti Ọlọrun" (1 Kọrinti 6:20).**

## Wiwà ni Iṣọkan

Paulu Apọsteli jẹ́ onitara oniwaasu. O ni iwuwo ọkàn fun gbogbo eniyan, o jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ajihinrere ti o tayọ ninu iṣẹ iranṣẹ wọn ni ilẹ ajeji ni gbogbo àgbaye. O ni Ẹmi Ọlọrun ninu igbesi aye rẹ̀, gbogbo awọn eniyan ti o tẹti silẹ si iwaasu rẹ̀ ni o n ni idalẹbi fun ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn wọn, ti wọn si n gbadura fun igbala. O dá Ijọ silẹ ni ilu pupọ.

Ki i ṣe didùn inu Satani pe ki awọn Ijọ Jesu Kristi maa fi alaafia sin Ọlọrun. Nigba ti Ẹmi Ọlọrun ba bẹrẹ si ṣiṣẹ laaarin awọn eniyan ti o ni itara lati jere ọkàn fun Jesu, Satani yoo wá lati mú ohun idiwọ wá.

Nigba ti Paulu kọ iwe si Ijọ Kọrinti, o sọ ọpọlọpọ ohun rere gbogbo ti o ti ṣẹlẹ laaarin wọn; ṣugbọn o tọka si awọn nnkan wọnni ti wọn ṣe ti kò tọ́. O wi pe, "Mo gbọ́ pe, iyapa mbẹ lãrin nyin." O wi pe awọn nnkan wọnyii kò yẹ ki o ri bẹẹ.

Bibeli wi fun wa gbangba pe iṣọkan gbọdọ wà ninu Ijọ, ki Ẹmi Ọlọrun ba le ṣiṣẹ laaarin wa. Jesu gbadura bayii fun awọn ọmọlẹyin Rẹ̀: "Ki gbogbo nwọn ki o le jẹ ọ̀kan; gẹgẹ iwọ, Baba, ti jẹ ninu mi, ati emi ninu rẹ, ki awọn pẹlu ki o le jẹ ọ̀kan ninu wa: ki aiye ki o le gbagbọ́ pe, iwọ li o rán mi" (Johannu 17:21). Nigba ti iṣọkan ba wà ninu Ijọ, awọn eniyan yoo mọ̀ pe Jesu pẹlu wa nibẹ.

## Yiyẹra fun Awọn Ẹni Ikọsẹ

Nigba miiran wahala ti ó n wá saarin Ijọ a maa pọ̀ pupọ to bẹẹ gẹẹ ti a fi n ti awọn ẹlomiran sode kuro ninu Ijọ. Paulu wi fun awọn Onigbagbọ ti o wà ni Romu pe: "Ẹ mã ṣọ awọn ti nṣe iyapa, ati awọn ti nmu ohun ikọsẹ̀ wá lodi si ẹkọ́ ti ẹnyin kọ́; ẹ si kuro ni isọ wọn" (Romu 16:17). Ohun ti o rọrun ni pe bi ẹni kan ba ti n gbọ́ ẹ̀sun si ẹlomiran nigba kuugba ki oun paapaa bẹrẹsi ni ẹsùn kan naa ninu ọkàn ara rẹ̀. Ọna ti o dara jù lọ ti eniyan le fi bọ́ kuro ninu ẹmi wíwá si ni lẹsẹ ni lati yẹra kuro lọdọ awọn ti o ni in.

## A fi Awọn Ẹni Rere hàn

Paulu wi fun awọn ara Kọrinti pé nigba ti iyọnu bawọnni ba dide laaarin Ijọ, awọn ọmọ Ọlọrun ni lati mú iduro wọn lati kọju ija si aitọ́. O wi pe, "Kò le ṣe ki o má si adamọ pẹlu larin nyin, ki awọn ti o daju larin nyin ba le farahàn" (1 Kọrinti 11:19). Awọn eniyan rere yoo fara hàn nigba ti a ba fi wọn wé awọn eniyan buburu.

Ọ̀kan ninu awọn ohun ti o mú iyapa wá ni pe ki i ṣe gbogbo awọn eniyan ti o wà ninu Ijọ ni o gbagbọ́ pe Ọlọrun ni Jesu i ṣe. O ṣe ohun danindanin lọpọlọpọ lati gbagbọ́ pe Jesu ni Kristi ti Ọlọrun rán. Ohunkohun ti o ba yatọ si pe ki a fi gbogbo ọkàn wa gbagbọ́ pe Ọlọrun ni Jesu ati pe Jesu ni olori Ijọ, yoo mú iyapa wá.

## Gbongbo Mulẹ

Titako irin wa gẹgẹ bi Onigbagbọ yoo ràn wa lọwọ lati fẹsẹ mulẹ ṣinṣin ninu igbagbọ, bi a bá fi tọkantọkan wa fẹ́ Oluwa. A ti gbọ́ apẹẹrẹ igi ti o n hù lẹba okun nla nibi ti afẹfẹ nla ati iji lile ti n bi lu igi naa. Awọn gbongbo rẹ̀ wọnu ilẹ lọ ṣinṣin lati le di igi naa mú. Igi miiran wà labẹ aabo rẹ̀ o si hù daradara; ṣugbọn nigba ti a mú aabo ori rẹ̀ kuro, iji lile ti o kọkọ fẹ lu u wo o lulẹ, nitori gbongbo rẹ̀ ko walẹ jìn. Bi a ba n fi igba gbogbo kẹ́ Onigbagbọ, ti a si n sọ ohun ti o tẹ́ ẹ lọrun nigba gbogbo, gbongbo rẹ̀ ki yoo le walẹ jìn. Ṣugbọn bi o bá fẹran Oluwa ni tootọ, awọn iṣoro ti o ba de ba a yoo tubọ sọ ọ di alagbara fun Kristi ti o ra a. Yoo le fara da awọn iṣoro naa.

Bibeli sọ fun wa bayii nipa Jesu: "Ẹni, nigbati a kẹgan rẹ̀, ti kò si pada kẹgan; nigbati o jiya, ti kò si kilọ; ṣugbọn o fi ọ̀ran rẹ̀ le ẹniti nṣe idajọ ododo lọwọ" (1 Peteru 2:23). Oun kò wa ẹtọ Rẹ̀. O fi ohun gbogbo le Baba lọwọ, ẹni ti yoo fi iya jẹ gbogbo awọn wọnni ti o jẹ Kristi niya ni akoko ti o tọ́.

A sọ fun wa pe ki a dabi Jesu. Paulu Apọsteli fẹ lati dabi Jesu, ani, ninu awọn iya ti O jẹ. O wi bayii pe: "Ki emi ki o le mọ̀ ọ, ati agbara ajinde rẹ̀, ati alabapin ninu iya rẹ̀, nigbati mo ba faramọ ikú rẹ̀" (Filippi 3:10). Igba pupọ ni Paulu n sọrọ lori ọran yii. Nigba ti o kọwe si Timoteu, o wi pe: "Bi awa ba farada, awa ó si ba a jọba: bi awa ba sẹ́ ẹ, on na yio si sẹ́ wa" (2 Timoteu 2:12).

**Igberaga**

Idi miiran ti wahala fi wá saarin Ijọ Kọrinti ni pe gberaga ti wọ inu awọn miiran nitori awọn ẹ̀bun ti Ọlọrun fi fun wọn. A fun wọn ni ẹ̀bun wọnyii lati fi gbé Jesu ga, ki i ṣe eniyan. A fi ẹbun iyanu fun awọn ẹlomiran gẹgẹ bi olukọni – ani lati kọ́ ni ni ẹkọ nipa Jesu. Awọn ẹlomiran jẹ́ oniwaasu olohun iyọ -- ṣugbọn a fun wọn ni ẹ̀bun yii lati maa kọ́ ni bi a ti ṣe le ri igbala. Awọn ẹlomiran ni ẹ̀bun imularada -- ṣugbọn ni orukọ Jesu ni wọn fi le ṣe iwosàn. Wọn kò ni ohun kan ti wọn fẹ funnu nipa rẹ̀. Kò si ẹni kan ti o le ṣe ohun kan fun Jesu afi bi Ẹmi Ọlọrun ba n ṣiṣẹ ninu rẹ̀.

**Fifi Ẹmi Mimọ wọni**

Ẹbun Ẹmi Mimọ́ jẹ́ ibukun ti o yani lẹnu pupọ. Agbara lati oke wá n sọkalẹ si ọkàn ti a ti sọ di mimọ́. Ẹmi Ọlọrun yoo sọrọ jade lati ẹnu ẹni ti o ni iriri yii, ni ede ti oun kò mọ̀ ri. Eyi ni olubori iriri ti o n pese Onigbagbọ silẹ fun iṣẹ isin fun Oluwa, o si jẹ ohun ogo lati ri iriri yii gbà. Sibẹ kò si ẹni ti o tun le wà ni irẹlẹ ju igba ti o kọkọ ri iriri yii gbà lọ. Kò si ohun ti o le fi ṣogo.

Gbogbo awọn ti o ba fẹ ṣiṣẹ fun Jesu ni lati wà ni irẹlẹ tootọ. Bi a ba fẹ jẹ́ ẹlẹri ti yoo ṣe aṣeyọri fun Jesu, a gbọdọ jẹ́ ki ẹwà Jesu ki o hàn lara wa. A gbọdọ fi ara wa si ipò ti awọn ti a n ba sọrọ nipa Jesu yoo fi gbagbe wa, ṣugbọn ti ọkàn wọn yoo maa rò nipa Olugbala ti a duro fun.

Nigba ti Peteru ati Johannu wo ọkunrin ti o wà ni Ẹnu Ọna daradara ni sàn, wọn wi pe: Ẽṣe ti ẹnyin fi tẹjumọ́ wa, bi ẹnipe agbara tabi iwa-mimọ́ wa li awa fi ṣe ti ọkunrin yi fi nrin?" (Iṣe Awọn Apọsteli 3:12). Wọn fi ye awọn eniyan pe igbagbọ́ ninu orukọ Jesu ni o mu ki iṣẹ iyanu yii ki o ṣe. "Ati igbagbọ́ nipa rẹ̀ li o fun u ni dida ara ṣáṣa yi li oju gbogbo nyin" (Iṣe Awọn Apọsteli 3:16).

Pẹlupẹlu, Ẹmi Mimọ funra Rẹ̀ yin Jesu logo. Jesu wi pe: "Ṣugbọn nigbati on, ani Ẹmi otitọ ni ba de, yio tọ́ nyin si ọ̀na otitọ gbogbo; nitori ki yio sọ ti ara rẹ̀: . . . . On a ma yìn mi logo" (Johannu 16:13, 14). A n fun wa ni ohun gbogbo ti a n ri gbà lati Ọrun ki a ba le fi yin Jesu logo.

Ọna ti a fi le yin Jesu logo ni lati sọ fun awọn ẹlomiran nipa Rẹ̀, ki a si jere ọkàn si Ijọba Kristi. Iṣẹ wa layé ni lati gbé ijọba Rẹ̀ kalẹ. Bi o ba ṣe pe a kò ni iṣẹ lati ṣe fun Jesu ni ayé yii, Oun yoo mu wa lọ si Ọrun ni gẹrẹ ti a ba ti gba ẹbun Rẹ̀.

**Fifi Ede Titun Sọrọ**

Bi o tilẹ jẹ pe fifi ede titun sọrọ jẹ́ ẹri fifi Ẹmi Mimọ́ wọni, sibẹ awọn ẹlomiran ti tabuku si ami yii. Awọn ẹlomiran ka fifi ede iyanu sọrọ si ju ki a gbé igbesi ayé ìwa mimọ́ tabi ki a ni ẹ̀bun agbara fun isin lọ. Nipa bayii, wọn di alaṣerege; Satani ti n fi igba pupọ lo iru ọna bayii lati tan ọpọlọpọ jẹ ki wọn le gba èke gbọ́.

Paulu Apọsteli wi pe, o ṣe ohun pataki lọpọlọpọ lati maa sọrọ laaarin Ijọ ni ède ti o yé ni. O ni o rọrun fun oun lati sọ ọrọ marun-un ti o yé ni ju pe ki oun sọ ẹgbẹrun ọrọ ti kò ye ni lọ. Sibẹ Paulu kilọ pe, a kò gbọdọ dá ni lẹkun ati maa sọrọ ni ede titun. Ṣugbọn a gbọdọ ṣe gbogbo rẹ lati fi gbé ogo Ọlọrun ga, ki iṣe ẹni ti n sòrọ. A gbọdọ ṣe ohun gbogbo tọwọtọwọ. Idarudapọ laaarin Ijọ a maa mú ẹ̀gan ba ilana Kristi.

**Iṣẹ́ fun Gbogbo Eniyan**

Ọlọrun ti pese iṣẹ́ silẹ fun gbogbo awọn ọmọ Rẹ̀ lati ṣe --ṣugbọn ki i ṣe iṣẹ kan naa ni O pese fun gbogbo wọn. Paulu Apọsteli wi pe ara kan ni Ijọ Ọlọrun, ṣugbọn ẹ̀ya kọọkan ni a fun ni iṣẹ ọtọọtọ lati ṣe. Oju wà fun iriran; eti wà fun igbọran; a n fi ika ọwọ́ wa kan nnkan; a n fi imu wa gboorun; a n fi ahọ́n sọrọ. A mọ̀ pe gbogbo nnkan wọnyii ni o ṣe pataki. Ṣugbọn a ri i pe ika ọmọdinrin wa ṣe pataki pupọ pẹlu, nigba ti o ba ni ipalara, ti a kò si le lo o. O le dabi ẹni pe irun ori wa kò ṣe pataki pupọ, ṣugbọn o ni ilo ti rẹ̀. O jẹ "ibori" ti o n mu ki ori wa mooru; Bibeli si wi pe "ogo" ni irun ori obinrin jẹ fun un (1 Kọrinti 11:15).

Nitori naa Paulu wi pe bi ẹya ara wa kọọkan ba ṣe pataki, gbogbo ẹya ara Kristi ni o ṣe pataki pẹlu. A kò gbọdọ sọ fun ẹnikẹni pe, "A ko ni fi ọ ṣe." Ọlọrun yoo san ẹsan fun olukuluku gẹgẹ bi ijolootọ rẹ̀ ni kekere tabi pupọ ti a fun un lati ṣe. Gbogbo ẹ̀bun ti Ọlọrun fi fun eniyan lati lò fun isin Rẹ̀ ni o ṣe pataki; sibẹ Paulu wi pe nnkan kan wà ti o ṣe pataki ju ẹ̀bun lọ. Eyi yii ni ifẹ pipe Ọlọrun ninu ọkàn, gẹgẹ bi a ti ṣe apejuwe rẹ̀ ninu 1 Kọrinti ori ikẹtala, ifẹ ti "a mã mu suru, a si mã ṣeun;…. ki iṣe ilara;…ki isọrọ igberaga, ki ifẹ̀, ki ihuwa aitọ́, ki iwá ohun ti ara rẹ̀, a ki imu u binu, bẽni ki gbiro ohun buburu, ki iyọ̀ si aiṣododo, ṣugbọn a mã yọ̀ ninu otitọ; a mã farada ohun gbogbo, a mã gba ohun gbogbo gbọ́, a mã reti ohun gbogbo, a mã fàiyarán ohun gbogbo." (1 Kọrinti 13:4-7). Bi olulukulu ẹni ti o pe ara rẹ̀ ni Onigbagbọ, ba le rin gẹgẹ bi ofin yii, ki yoo si iyapa laaarin Ijọ.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni n mu ibukun Ọlọrun wá sori Ijọ Ọlọrun?

2 Darukọ ọ̀kan ninu awọn iyọnu ti o wà ninu Ijọ Kọrinti.

3 Ki ni yẹ ki a ṣe nipa awọn ti o n mu iyapa wá saarin Ijọ?

4 Ki ni awọn ohun ti awọn ara Kọrinti fi n ṣe igberaga?

5 Iru iwa wo ni Jesu hù si awọn ti o jẹ Ẹ niya?

6 Eredi rẹ̀ ti a ṣe n fi Ẹmi Mimọ wọ wa?

7 Ki ni ami kan ti a n fi fun wa nigba ti a ba ri Ẹmi Mimọ gbà?

8 Bawo ni Paulu ṣe fi Ijọ wé ara eniyan?

9 Ki ni iṣẹ Onigbagbọ ni ayé?

10 Ki ni ṣe pataki ju "ẹ̀bun"lọ?